# BI A TI ṢE KỌ LẸTA

# ỌRỌ IṢIWAJU

GBOGBO wa ni a fẹ lati mã ri lẹta gbà. Ṣugbọn a ko le ni ireti pe a o mã ri ọpọlọpọ iwe bẽ gbà, bi awa nã ko ba nkọ si enia.

O buru pe ni apa ilu wa yi, ogunlọgọ enia li o wà ti ko mọ iwe kọ rára, tabi ti o jẹ pe oye diẹ ni nwọn ni nipa bi a ti ṣe kọwe si enia li ọna ti o dara.

Nitori awọn enia wọnyi ati ni pataki nitori awọn agbalagba wọnni, li ọkunrin ati li obinrin ti nwọn ṣẹṣẹ kọ iwe kika ati iwe kikọ tán ni a ṣe ṣe iwe kekere yi.

Njẹ ninu iwe yi ni ẹ o ti ri awọn ilana kekeke melokan ti yio fi ye nyin bi a ti ṣe kọwe si ẹnikeji. Bi ẹ ba fi ibaralẹ ati oye ka wọn, ki yio pẹ ki ẹ to le mã kọ iwe si enia li ọna ti o dara.

A dupẹ lọwọ Ọgbẹni E. A. L. Gaskir, Yoruba Literature Committee, Ibadan, ati Ọgbẹni J. O. Fanẹyẹ fun ãyan wọn lori iwe yi. Ṣugbọn aṣiṣe ti o ba wà ninu iwe yi jẹ ti J. S. Ogunlesi.

*Ibadan*, **1948.**

# Awọn ohun ti o wa ninu Iwe yi

## Ori Kinni

*Oju Iwe*

Idi rẹ ti o fi tọ́ ki a mã kọ Lẹta si enia fun ara ẹni .. .. .. .. .. .. 4

ORI KEJI

Oniruru ipa ti mbẹ ninu Lẹta .. .. 7

ORI KẸTA

Bi a ti şè bẹrẹ Lẹta ati bi a ti şẽ pari rẹ 13

ORI KẸRIN

Oniruru Lẹta ti a nkọ .. .. .. .. 15

ORI KARUN

Apẹrẹ oniruru Lẹta miran .. .. .. 20